IKEDE

Igida, eiyẹ fo, eniti ko loyun ri ti di ọlọmọ lọsangangan yio jade ninu iwe Irohin Imọle ọsẹ ti o mbọ. E roju ole, e ko mu, ọmọ nyin ko feraku, o ngbe ọmọ wa'le.

Gbọmọ f'ọlọmọ alagbatọ ko mọ'yi ọmọ.

IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

OWE

Bi owe bi owe ni a nlu ilu Agidigbo, Ọlọgbọn ni njo o o, Ọmọran ni mọ ọ, Nitoripe ewe koko ni nwọn fi se awọ re, igi gonmugomu ni nwọn fi nlu u beni ko gbọdọ faya ko si gbọdọ ma dun.

VOL. VI No. 349 MONDAY SEPTEMBER 24 — SEPTEMBER 30 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# ỌDA-OWO TI BẸRẸSI DA ẸGBẸ ỌLỌMỌJUKUTU

Awo ti bẹrẹsi ya, oogun si ti bẹrẹsi tan ninu ado awọn Oloto ẹgbẹ Ọlọmọjukutu "U. P. P." ti nwọn sẹsẹ da silẹ laiti pe osu mẹrin ti nwọn da ẹgbe na silẹ.

Onirohin wa sọ wipe, nwọn ko ri owo osu san fun awọn Oṣiṣẹ ile-itewe Irohin wọn mọ. A ti pelu pe nwọn ti da gbese repete ti o to nkan bi ẹgbẹdogun ponun (£3,000) lori owo ti nwọn ko ri san fun awọn Akọwe Igbimọ Ẹgbẹ wọn.

Akọwe Akode–iṣẹ Ọlọmọjukutu igboro (Organising Secretary) ko ri owo gba mọ. Gbogbo awọn Oṣiṣẹ ẹgbẹ na ti o wa ni Ẹku mọkandinlọgbọn bi ONDO, IJẸBU ati EKITI ko ri owo iṣẹ gba mọ, awọn awamoto wọn paapa ti fa moto wọn kalẹ fun wọn nigbati nwọn ko ri owo osu gba.

Nigbati ọrọ Ọda-owo yi ko ni iyanju mọ, ni Ọgbẹni Mukaiulu Oduwọle, Akọwe-Igboro Ẹgbẹ na ba sare wa ba Oba C. D. Akran ni ile re ti o wa ni 197, Igbosere Road l'Eko pe:—

"Awo ti bẹrẹsi ya, oogun si tan ninu ado, na ati awọn Oṣiṣẹ on ko ri owo mọ o"



*OLOYE S. L. AKINTỌLA*
*Olori Ẹgbẹ (U. P. P.)*

Lẹhin ti nwọn se alaye fun ara wọn tan lori ọrọ na, ni nwọn ba bẹrẹsi san adebu-owo fun awọn Oṣiṣẹ na, awọn ti nwọn ngba owo-osu bi ponun mẹtalelọgbọn sile mẹfa ati kobo mẹjọ (£33 / 6 : 8d) eni kọọkan gba ponun mẹwa-mẹwa, awọn ti nwọn ko gba owo to bẹẹ si gba ponun marun-marun owo idaporo, ni ikẹhin gbogbo rẹ, nwọn tun gba moto ti nwọn wọ debẹ kalẹ lọwọ wọn.

Onirohin wa fi ye wa siwaju pe, ọran ọda-owo yi ko mọ lẹnu ibẹ nikan fun Ẹgbẹ Ọlọmọjukutu, ọran na sẹsẹ bere ni, to bẹẹ ti nwọn fi da adọta enia duro lẹnu iṣẹ ninu awọn Oṣiṣẹ ile itẹwe wọn "THE PEOPLE STAR PRESS" ati ti "IWE IMỌLẸ OWURỌ"



*Ọgbẹni Makaiulu Odiwọle*
*Akọwe Igboro Ẹgbẹ (U.P.P.)*

Nigbati Onirohin wa si lọ wadi ọran na lẹnu Oloye A. M. A. Akinloye ti iṣe Alaga Ile-itẹwe Ẹgbẹ U. P. P. na, Oloye na jẹwọ wipe lotitọ ni awọn ti da idaji enia duro ninu awọn Oṣiṣẹ ile-itewe wọn na, ṣugbọn ki iṣe otitọ ni pe awọn ko san owo osu fun wọn lati osu meji sẹhin.

Idi ọrọ re o! A sẹsẹ tọ ọti wo, okun bantẹ ja o.

BRAZIL:- Ọgbẹni Senhor Hermes Lima ti di alakoso Ijọba, nitoripe Ọgbẹni Senhor Francisco Brochado Da Rocha ti fi ipo alakoso Ijọba silẹ.

RHODESIA:- Nwọn ju okunrin kan l'oko pa, nwọn si se enia mọkandinlogun lese ninu ija kan ti o sẹlẹ larin ilu.

xx YABA:- Ọdaran apẹlewọn kan ti awọn Ọlọpa sọ wipe o ti lọ sewọn nigba meje, Nya Bassey ati Effiom Ephraim, ni adajọ se idajọ pe ki nwọn lọ si ẹwọn ọdun marun-marun nitoripe nwọn jẹbi ẹsun pe nwọn ji Igbaolemerinla ponun ati sile mẹdogun (£214 : 15/-).

# ALAKE DI ẸNI ADỌRUN ỌDUN



*ALAIYELUWA LADAPỌ ADEMỌLA KEJI,*
*Ọba Alake Abẹokuta*

IROHIN ko to afojuba ni aseyẹ ọjọ ibi ti Ọba Kabiyesi Alaiyeluwa, Ladapọ Ademọla keji, Alake Abẹokuta se ni ọjọ Ọjọbọ ti ise ogunjọ osu yi lati se iranti adọrun ọdun ti o de ile aiye ati wipe ọdun yi lo di ọdun kejilelogoji ti o de ori oye.

Gbogbo awọn Oṣiṣẹ ọba ti o wa ni Abẹokuta ati agbegbe rẹ ni ko lọ si ibi–iṣẹ ni ọjọ na. Ni kutukutu owurọ ni awọn ọmọ ogun Naijiria ati awọn Ọlọpa Ijọba Ibilẹ ti duro wai-wai si afin Ọba ti nwọn si bẹrẹ si fun fere. Alaiyeluwa na ba yan un kọja niwaju awọn Ṣọja ninu ọla nla rẹ.

Nigbati o di irọlẹ gbogbo awọn ọmọ ile–iwe ni nwọn sere ni gbangba ọdan Abẹokuta. O dabi enipe ki ilẹ ọjọ na ma su mọ. Aseyẹ ọjọ na kanmọmọ o le gongo.

Awa Oniwe IROHIN IMỌLẸ ki Ọba Kabiyesi Alaiyeluwa Ladapọ Ademọla keji ku ajọ dun. A seyi samọdun o.

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

Ogun ti arọ ti gbọ tẹlẹ wipe o mbọ, bi arọ na ba tete bẹrẹsi salọ lati igba na, o daju wipe nigbati ogun na ba de ko ni ri arọ na pa, Nitorina yẹ irawọ rẹ wo ki o si mọ ohun ti yio ṣẹlẹ si ọ larin ọsẹ yi.

**ARIES (Mar 20 - Apl 21)** Ọrẹ kan ti o ti mbẹ nilẹ fun ọjọ pipẹ, ọsẹ yi lo yẹ ki o da ọrọ na silẹ ni siso.

**TAURUS (Apl 22 - May 22)** Iṣọra di owo rẹ larin ọsẹ yi, ki o si ṣe pẹlẹpẹlẹ pẹlu gbogbo ohun ti o nṣe nitori ijafara lewu.

**GEMINI (May 23 - June22)** Bi o ba nṣe Ọna yio dara fun ọ b a k a n a ni yio dara fun ọ bi o ba nṣe iṣẹ ọgbọn ori.

**CANCER (June 23 - July 23)** Iṣẹ rẹ yio yọnri si rere bi o ba le ni ifọriti, ki o ma a gba ọrọ si Agba lenu.

**LEO (July 24 - Aug 23)** Owo yio wọle wa fun ọ lati ode ju inu ile lọ larin ọsẹ yi.

**VIRGO (Aug 24 - Sept 22)** Ṣe suru ki o si jẹki ẹsẹ rẹ duro gbọin-gbọin, iwọ yio jere pupọ ju adanulọ.

**LIBRA (Sept 23 - Oct 22)** Tunbọ mura siwaju, ere pupọ mbẹ fun ọ laipẹ.

**SCORPIO (Oct 23 - Nov 22)** Ṣọra lọdọ a w ọ n obinrin ki nwọn ma ba a tan ẹ jẹ larin ọsẹ yi.

**SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22)** Fi gbogbo ọkan rẹ sipa ire ati anfani ti o mbọ wa ba ọ ninu ọsẹ yi.

**CAPRICORN (Dec 23 - Jan 20)** Maṣe jẹ enia lile beni ki o maṣe jẹ rirọ ju, ki o jẹ ko gbona, ko tutu.

**AQUARIUS (Jan 21 - Feb 19)** Jẹki awọn ohun rere gbogbo ti o fẹ pọju ninu ọ k a n rẹ ju eyiti o nfi oju ri lọ.

**PISCES (Feb 20 - Mar 19)** Ọpọ owo lo mbọ wa tẹ ọ lọwọ ṣugbọn nṣe ni ki o dina ibiti owo na ngba fọlẹ.

# Igbomina, Ọffa, Ekiti ati Odo-Ogun di eegun ẹja, o ha Ilọrin lọrun

*Lati Ọwọ:— M. A. ỌDẸKUNLE*

Mo ki gbogbo ọmọ ilẹ Igbomina, Ọffa, Ekiti ati Odo-Ogun, lọmọde ati lagbalagba pe, ẹ ku ọrọ ilu, ilẹ na ti ẹ nja fun Ọlọrun yio jẹ ko san gbogbo wa sowo ati sọmọ pẹlu.

Mo tun ki gbogbo ẹnyin agbagba Igbomina, wahala ati i n a w o nyin Ọlọrun Ọba ti nsan ẹsan rere fun awọn ti nja f u n Ominira ilẹ wọn yio san ẹsan rere fun nyin ni ọ n a aimoye, bakanna mo tun ki gbogbo ẹnyin ẹlẹgbẹ mi ti ẹ nja futafuta l o r i ilẹ wa wọnyi, Ọlọrun Alanu yio ran gbogbo wa lọwọ Amin. Ominira na yio si to wa lọwọ pẹlu alafia.

Ilọrin gbọ pe Igbomina Ọffa ati Ekiti fẹ gba Ominira, nwọn ran'ri, kiniṣe ti ẹ taku? Ẹnyin ara Ilọrin, nwọn ki t a k u. Hal ẹ ṣe, ẹnyin a r a Ilọrin, ọrẹ ni Ilọrin ati awọn ilu ti mo darukọ wọnyi, ore ni a si ṣe f u n nyin, a ki ṣe ẹru nyin kẹ. Bawo lo ti wa ri ti atako na fi pọ tobẹ pe ao ni gba Ominira? Ha a a! o yẹ kẹ ni suru, kẹ fọwọ wọ inu. Ohun ti o yẹ kẹ ṣe ẹnyin ara Ilọrin, nigbati ẹ gbọ pe ao gba Ijọba tiwa lọtọ, ohun ti o yẹ nipe kẹ pe wa, kẹ dupẹ fun wa pupọ pe a sin ẹnyin na de ibi ti ẹru ko ni ba nyin mọ, kẹ si fun wa ni adura pe ki Ọlọrun jẹki Ominira na tu wa lara. Ṣugbọn nisisiyi bẹ fẹ, bẹ kọ, Ọffa, Ekiti ati Igbomina ti di eegun ẹja nwọn ti ha nyin lọrun ao gba Ijọba tiwa lọtọ lagbara Sadauna Sokoto ati lagbara Allah. Ẹ ko ba tiki kẹ fọrun gunlẹ, yẹyẹnatu ni gbogbo o h u n ti ẹ nṣe.

Minista M. A. O. Ọlanrewaju mo ki ọ, Hon. P. B Ọlatunde mo yin ọ, Hon. O. Afọlayan sara tẹ re o, ẹ maṣe jafara, ẹ tubọ tẹ siwaju ka le gbade iye.

Gbogbo Igbomina, Offa Ekiti, ati Odo-Oogun mo ki nyin pupọ ẹ maṣe jẹ ko su wa, ki ẹ si ṣe lakaye pupọ, nitori a w ọ n Ilọrin nsọ wipe ọwọ ara wa la o ma a fi g b a r a wa leti ṣugbọn nwọn npurọ ni o'

Otitọ ni y i o bori eke lorukọ Ọlọrun Ọba.


# KERE O! KERE O !!

KURANI L'EDE YORUBA TI DE

**A nta Kurani Ọgbọn-Ẹṣu ti a ṣe Larubawa ati itumọ rẹ l'ede Yoruba. O wulo fun ẹnikẹni 25/- Postage 1/6d**

Iwe Egbogi iwosan Ataiyebaiye, o kun fun Awure, a le ri itumọ Ala ati ohun t'oba runiloju ninu Odu merindinlogun ninu iwe kanna 10/6d Postage 9d

TETE FI OWO TIRẸ RANṢẸ SI:—

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE.

*8, IDUMAGBO AVENUE, LAGOS, NIGERIA.*



## KEREO! AKIYESI PATAKI

Awa na le jẹri wipe Ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, awa na nlo ni Gold Coast (Ankara) Ghana pẹlu, meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




## Irohin kakiri Igboro IluEko

Bẹ na ni ẹwẹ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia t'ọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn jẹ nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti awọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ Ojulowo giriki ati adamase fun iwosan "JẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹna ni awọn le tun fi owọ soya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi I/o, Igbe ẹse tabi aiko ri igbonse deede. Inu rirun mgbakugba, ara wiwo. Ecanri, Ẹhin didun, Oju siṣan, tabi aiko riran kedere kokoro burukụ lara, Osi inu Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo E g b o g i LEOPILLS nitoripe o si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA L'OGUN ỌRỌ, IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

**IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:-** Igo nla ṣile mẹfa abọ (6/6d) pere ni, Igo kekere ṣile mẹta abọ (3/6d) pere ni.

Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Amodi ti o ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**

8. Palm Church Street, P. O. Box. 333. Lagos Nigeria. Phone 22878, ati pẹlu ni Ṣọbu awọn arabinrin Mrs. C. O. Babajide near Health office Ibadan ati ni A b i m b ọ l a Medicine Store F29 Okesha Street Ilesha. Bisale Medicine Stores, British & Foreign Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOKOJO STREET, IBADAN N.

**AKIYESI:-** Ri daju gbamgba wipe Ṣọbu ti nwọn nta lo gbe ranṣẹ lọ ra, bi bẹ kọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta Adamọdi tabi orisi omiran fun ọ o, maṣe gba rara o.

# EYI NI AWỌN ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

## ỌJỌ AJE SEPTEMBER 24 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja, Agege, Ebute-Ero, Ọjọ Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunlẹ, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha-Ijẹbu, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi, Ifaki |

## ỌJỌ IṢẸGUN SEPTEMBER 25 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Ibẹrẹkodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbe, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode - Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Ọja - Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ'RU SEPTEMBER 26 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun - Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedẹji, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Isara, Imodi, Ishan |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo—Aiyedun |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ SEPTEMBER 27 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abulabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowo, Tẹmidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun - Ọwa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJESHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EIKTI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ẸTI SEPTEMBER 28 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Agege, Ikeja |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajeganlẹ, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupon, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha, Ijẹbu, Iṣara Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun Ijẹbu.-Ijẹsha |
| EGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi, Ifaki, |

## ỌJỌ ABAMẸTA SEPTEMBER 29 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Ibẹrẹkodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Rẹmọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Ọja—Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ AIKU SEPTEMBER 30 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, It ori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedẹji, Ogburo, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe, Ishan, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ, Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo - Aiyedun |

## ỌJỌ AJE OCTOBER 1 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagry |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowọ, Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa, Erunwa Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

*Lati Ọwọ EJON'GBORO*

### CALABAR

Idaamu nla ba gbogbo awọn ara abule Nakanda nigbati nwọn ji lowurọ ti nwọn si ba obinrin kan, Nkoyo Effiong ninu agbara ẹjẹ, ti ẹnikan gun lọbẹ ni gbogbo ara. Ti o si ti ku si ori ibusun rẹ awọn Ọlọpa nwa ẹniti o hu'wa aidara na lọwọ bayi.

### FRANCE

Awọn Ọlọpa ti mu awọn enia mẹrin ninu awọn enia mẹwa ti nwọn gbimọ pọ lati pa alakoso Ijọba wọn Ọgbẹni De Gaulle.

### JAMAICA

Ọlọla Alexander Bustamante alakoso Ijọba Jamaica ẹni ọdun mejidinlọgọrin gbe Ọdọmọbinrin kan, Gladys Maud Longeridge ẹni ọdun mẹtadinlọgbọn ti o i-ṣe iṣẹ akọwe ni Ọfisi rẹ ni iyawo,

### O'SHA

Idaamu nla ba gbogbo awọn oṣiṣẹ kotu nigbati nwọn ba oku iyawo ile kan ninu kotu ni kutu-kutu owurọ ti awọn kan ti pa, ti nwọn si tẹ oku rẹ silẹ ni ihoho bi ọmọluwabi bi o ti ṣe waiye. Nwọn da oju rẹ bo'lẹ, nwọn si ko ọwọ rẹ mejeji sẹhin rẹ.

Awọn Onisẹ wolewole ti gbe oku rẹ lọ si ile iwosan lakulakuni awọn Adajọ kotu ba nba iṣẹ wọn lọ

### EKE ORUGBE

Gbogbo ilu gbojikan fun ariwo ẹkun nigbati obinrin kan, Benicy Onyeama fẹ kọja si odikeji ọja ti o si ṣe konge agbako mọto, ti mọto na si tẹ pa patapata larin-ọja. Awọn Ọlọpa ti gbe oku rẹ lọ si ile-iwosan lakulaku.

### KANO

Idamu nla ba awọn Ọjẹṣ Ọlọrun Ijọ Aguda nigbati awọn ole kan wọ ọgba wọn lọ ti nwọn si ji ọti Oyinbo ti nwọn fẹ fi jẹ onje alẹ Oluwa .

### LOS ANGLES

Obinrin kan, Film Star Linda Darnell ti pe Ọkọ rẹ Merle Robertson lẹjọ ikọsilẹ ni Kotu. O ni Ọkọ on ko ni oju a anu, o tun le mu Ọti pupọ ati wipe o tun nko awọn obinrin miran kiri yato si on iyawo rẹ.

### PORT-HARCOURT

Bi enia jẹ ori ahun a ke, ti o ba ri i bi awọn kan ti ṣe ge Ọmọ enia si wẹwẹ bi ẹran sura a, ti nwọn si gbe e si oju irin Ọkọ reluwe ninu Ọsẹ yi.

Awọn Ọlọpa nṣe iwadi awọn ti o pa Ọkunrin na.

### EKO

Ipade Igbimọ Ijọba Apapọ berẹ l'Eko ni oni ti iṣe Ọjọ kẹrinlelogun Oṣu yi, fun imura silẹ Alakoso Ijọba India.

### EKO

Awọn ara Eko yio dibo yan awọn aṣoju miran sinu ile Igbimọ alaṣẹ Eko (L. T. C.) ni ọjọ kẹdogun Oṣu ti mbọ.

### LỌNDỌNU

Ọjọgbọn Dokita Ian Aird, ti o sise abẹ fun awọn Ọmọ meji ti nwọn dipọ ni Ọdun 1953 Boko ati Jomo, ti o si tun sisẹ abẹ fun awọn Ọmọ ti o lẹpọ ti nwọn gbe lọ ilu Oyinbo laipẹyi ku ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun Oṣu yi.

### PORT-HARCOURT

Ọgbẹni H. O. Nwazota, Adajọ Kotu giga, ṣe idajọ pe ki Ọdaran awakọto kan Sylvester Nwobodo lọ san adọta pọnun (£50) si Kotu tabi ki o lọ si ẹwọn Oṣu mẹrin nitoripe o ko awọn ero meje dipo ero marun ti Ijọba fun un laṣẹ lati ma a ko.

## ỌRỌ OLOTU

Lati ọwọ ewe kọji

Lọsẹ to kọjayi ni awọn enia tun gbidanwo lati pa Dọkita Kwame Nkurumah, alakoso Ijọba Ghana, eyi si ni igbakẹta ti nwọn gbidanwo lati pa a. Nigbati nwọn wadi ọ r ọ na nwọn ri wipe ẹbiti ko p'era, ara ile ẹni lo nṣe'ni awọn ti nwọn jẹ aṣọ ara rẹ na lo nwa ipalara fun un. Eyi si mu ki Nkurumah paapa ma siye meji si ojiji ara rẹ nisisiyi.

Aiye di rudurudu ko si si ifọkan balẹ mọ. Iyawo npa ọkọ, ọkọ npa iyawo. Awọn Ọlọpa tun nri ori ọmọ enia marundinlogoji ninu iyara ọọkan soso larin ilu!

Eyi lo mu awa o n i w e IROHIN IMỌLẸ wipe ninu ewu lawa. Ki Ọlọrun ki o gbawa lọwọ awọn ikoriko enia ti nwọn fi awọ aguntan bo'ra.

ADVT. No. 151

Ṣe o ti lọ parọ owo atijọ ọwọ rẹ si

OWO TITUN

TI ILẸ NIJIRIA?

O le parọ owo pepa kọrẹnsi t'ọfẹ titi di ipari oṣu SEPTEMBER ti a wa ninu re yi.

Ti owo ẹile ati awọn owo wẹwẹ di ipari oṣu DECEMBER

## U. A. C. bori Dahọmi ni'lu Kutọnu

Eyi ni igba akọkọ ti awọn elere Bọlu U. A. C. bori awọn Dahọmi ni'lu Kutọnu nwọn na awọn Dahọmi ni meji. Awọn ero iworan lọjọ na to iwọn ẹgbaa, nṣe ni ori Ọdan na nho ti nwọn si npariwo ge-e-e-e. Iyin ọjọ na, ẹ jẹki a gba fun awọn elere bọlu U. A. C. ati aṣọle wọn Ọgbẹni Okonkwo.

Ni agogo marun irọlẹ ni ere na bẹrẹ ni gban-gbafili ni Kutọnu, awọn elere bọlu ti Naijiria dabira bi ko ba si ọgbọn ti awọn Naijiria dani, awọn Dahọmi ni iba bo ti ere na. Ohun ti nwọn ṣe na ni pe ni piparọ ipo ara wọn si ara wọn. Nṣe ni ariwo nsọ ge-e ti gbogbo awọn ero iworan nsala ti owọn si nkan sara si awọn ara ilẹ Naijiria. Ọlẹ meji ni awọn elere Naijiria gba lori irin ajo wọn na ki nwọn si to lọ, nwọn gba aṣẹ N. F. A. ati L. A. F. A. nwọn si gba iyi bọ wa si ile.

## Ọkunrin kan ṣa Iyawo rẹ l'ada

UMUAHIA Ọrọ di bi o ko lọ ki o ya fun mi, nigbati ọkunrin kan sare wọle ti o si bẹrẹsi ṣa iyawo rẹ ni iṣakuṣa, ni obinrin kan si sare jade wipe ki on gba Obinrin na silẹ.

Ọrọ ba di ebi npa Ejo, Ahun nyan; ati Ahun ati Ejo ẹran jijẹ. Ọkunrin na ko tilẹ wo ẹniti o fẹ gba iyawo rẹ silẹ, nṣe ni o gbe ada le e, ti o si tun ṣa a ni iṣakuṣa.

Awọn Ọlọpa sọ wipe, Ọkunrin na ba iyawo re ja, o si sọ wipe ki o maa lọ si ile wọn, ni Obinrin na ba ko ẹru rẹ, ti o si lọ si ile awọn enia rẹ.

Nigbati Ọkunrin na reti pe awọn obi rẹ fẹ de ti nwọn yio wa bere ohun ti o fa a ti on fi le e ni ile ti ko si ri wọn, ni o ba gbera o si lọ si ile wọn. Nigbati o de'bẹ, ko tilẹ bere ẹnikankan. Bi o ti ri iyawo rẹ ada ti o gbe soke bayi gige lo ge, eyi obinrin ti o ri i ti o si fẹ laja, o tun ge e lada. Igbẹ la fewe, oko la fẹlasa! Ni gbogbo awọn ara ile ba k'ere mọlẹ nwọn sisalọ.

Nwọn ti gbe awọn obinrin mejeji na Rebecca Kalu ati Odeh Okoruku lọ si ile iwosan Elizabeth ni Umahia fun itọju. Awọn Ọlọpa si nṣe iwadi ọrọ na lọwọ bayi.

## ẸGBẸ YORUBA TAJODE

EKO:— Irohin ko to afojuba ni irin ajo ti awọn Oloye Ẹgbẹ Asaro Yoruba ni Eko ati agbegbe rẹ lọ si Ipinlẹ Iwọ-Oorun Naijiria ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ keje oṣu yi. Ninu irin ajo wọn, nwọn de awọn ilu patakipataki bi, Ijebu-Ode, Abẹokuta, Gbọngan, Ilesha, Oshogbo, Iwo, Oyọ, Ile Ifẹ ati awọn ilu ti aye ko si lati darukọ wọn

Ninu ilu kọọkan ti nwọn ba de, n w ọ n nlo taara si ọdọ awọn Ọba ati Ijoye ilu. Nitoripe ajoji ki i wọ ilu ki Onile ma mọ. Ariki-Ariyọ ni ti ọmọ tuntun a w ọ n Kabiyesi Alayeluwa si nki wọn pẹlu ọyẹ. Awọn ọmọ ẹgbẹ na si nbere awọn n k a n ti ko ye wọn p ẹ l u ayọ ati inu didun ni awọn Ọba si fi nda wọn lohun.

Irin ajo na dun to bẹ gẹẹ ti o fi jẹ wipe ọjọ kẹjọ ri nwọn pada si Eko dipo ọjọ meje ti nwọn ti fẹ de tẹlẹri.

Pẹlu ayọ ati ara lile ni nwọn pada de ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi. Ẹ ku irin ajo o.

ADEMỌLA ADEBOMI
AKỌWE ẸGBẸ.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TỌNIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN EGBOGI AGBALAGBA ỌKUNRIN ATI OBINRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani li nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gesi pẹlu wọn to ṭẹlẹ, Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ re si daju bẹ yen mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dokita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ ati pe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣe ti o ko ba jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de bi kọn lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹ Ẹ-emi (breath) inu ko ba gunlẹ daradara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣẹ ko "NJẸ" fun wọn ni ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja Ọgbọn ọdun lọ si dede adọrin tabi jutẹ lọ mọ daju pe 'DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara re ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gte kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIAN MEDICINE STORES
TINUBU STREET, LAGOS PHONE:- 20278.

**Waterloo Medicine Stores,**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigerian, (Ọja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS,
48 WAKEMAN STREET PHONE 22878 YABA.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOL
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOBGO

*Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos ON olu: E. A. Adenji 24, Oliyide Street, Odu—Ahore Mushin.*